ỌBANIKORO TẸ OFIN L'ETI.

# EKO AKETE.

"EMI YIO FI OHUN TI O NDUN MAKUNNU HAN AWON ALAGBARA, NGO SI JE ALAGBAWI AWON ODI."—W. T. STEAD

VOL. VI. No. 300. SATURDAY, NOVEMBER 10, 1928. 4d.

The Leading Weekly Vernacular Newspaper in Nigeria.

22 NOV. 1928
LAGOS

## White's Radical Gonkiller.

:o:

(NATIVE.)

[*A complete cure for old and fresh Gonorrhoea.*]

When Gonorrhea is not properly cured, it gives rise to other troubles and diseases such as Barreness, Piles, Kidney Diseases, Stricture, Rupture, Rheumatism, Sore-eyes, etc.

N.B.—This Medicine cures Gonorrhea completely in either man or woman, so that no secondary diseases can follow.

Made from pure **Native Herbs**, and sold only by

VICTOR WHITE, ESQ., *Chemist.*

41, Offin Road, Lagos.

PRICE: **Ten Shillings (10/-)** per bottle.

*Packing and Postage 2/6d. extra, to all parts of Nigeria.*

---

EGBOGI ALAWOTAN ATỌSI.

:o:

[*Fun Atọsi lailai ati titun.*]

Ti a ko ba tete wo Atọsi san daradara, o ma ndi enia lọwọ abiamọ, o si ma nfa orişi arun mi wa, bi:—Jẹdi-jẹdi, Aran, Ipake, Ase, Lakuregbe, Arun Oju, ati arun mi.

N.B.—Egbogi yi nwo Atọsi san lawotan patapata, ko si nje ki o ri eye wu

# TO STOP YOUR ACHES & PAINS

*SIMPLY USE*




For more than 40 years Sloan's Liniment has been used throughout the World. It is kept handy in many thousands of homes to give quick, warming relief from the pains and aches of Rheumatism, Lumbago, Neuralgia, Sprains, Bruises and other severe pains. No need to rub Sloan's—it penetrates and kills the pain instantly.

*Sold by all Dealers.*

Wholesale:

FASSETT & JOHNSON, Ltd.
86, Clerkenwell Road,
London, England.

*Editor & Proprietor:—*
ADEOYE DENIGA,
*Office* 24, Williams Street,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RE.

| Eko. | | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*

## GBOHUN-GBOHUN.

INA LO WA FỌN NI TABI O WA WO ẸWIRI ALAGBẸDẸ?

Owe ti o bọ si wa lẹnu ni eyi nigbati a gbọ ti Oyinbo Alabojuto Eko Ile-iwe ti o lọ bẹ Ṣukuru kan wo ti o' jẹ eyiti awọn ọmọde binrin nlọ, a gbọ pe nigbati o de ibẹ ti o si ri bawọn ọmọde na ti nṣe si lẹhin igbati nwọn ki tan lọwọ tọwọ a sọ pe o bere lọwọ Iya-Afin ti o jẹ ọga ibẹ pe eṣe ti awọn ọmọ Ṣukuru rẹ kima sọ Yoruba, a si gbọ pe Iya-Afin na fun ni esi ti o wọ:

Ohun ti o ṣe ni loju su ni eyi ki Oyinbo Alabojuto Ẹkọ Ile-iwe labẹ Ọba ma sọrọ nipa pe ki awọn ọmọde ile-iwe giga ma sọ Yoruba ni Ṣukuru: ṣe ohun ti a sọ nijelo niyi pe Ofin Ile-iwe isisiyi ko dabi alara bi ti Ofin igba lailai nitori awa sehin t'ire ti Ofin na sọ Ẹkọ awọn ewe ode Oni da.

Nigbati o ba ṣe kẹrẹkẹrẹ awọn Oyinbo miran yio le fẹrẹ ma sọ pe ki awọn ewe Ṣukuru ma kọ iwe wọn ni ede Yoruba: a mọ pe pupọ mbẹ ninu awọn Oyinbo ode Oni ti nwọn ko ni ifẹ si pe ki awọn ọmọ Ile-iwe wa mọ iwe amọjinlẹ daindain mọ: ki nwọn ṣa ti gbọ ede Oyinbo okumarata meji mẹta bi *Boy, bring chop, A day cam Sah, Go for dem place for me, I lif for go Sah* ni nwọn nfẹ ki awọn ọmọ-ilewe wọnyi gbọ nitoto Ile-iwe giga pupọ le wa ni igboro sugbọn owo gerege ti nwọn ngba mbẹ fun Ẹkọ ko ti gajulọ lori Obi awọn ọmọ-ilewe miran ti ori wọn yo si iwe sugbọn ti owo tiantian yi le sa lati le kọ iwe nibẹ. Ni toto ẹra kọ fẹ pọpọ de'nu.

## ỌBANIKORO TẸ OFIN L'ETI.

Ninu Idajọ ti Adajọ H. S. Beckley ṣe ni ẹnu ọsẹ tokọja nipasẹ ti Ile Osugbo ni Ẹnu Ọwa eyiti Adajọ na da Oloye Ọbanikoro lare ẹjọ ti awọn apakeji pe, a gbọ pe Adajọ kanna yi sọpe fifi ipa ṣi ilẹkun Ile Osugbo na eyi ti a sọpe Ọbanikoro ṣe jẹ ohun ti o ku diẹ ki o to, nitoripe irufẹ iwa bẹ le bi awọn ti o pe ẹjọ na ni inu o si jẹ ohun ti ko tọ sina ninu ofin. Adajọ ko si paṣe pe ki Ọbanikoro yi gba owo-irin ẹsẹ lọwọ awọn ti nwọn pe e lẹjọ na!

AWUJALẸ D'AFỌMỌ O D'ẸIYẸ.

A gbọ pe Awujalẹ Ọba Ijebu-Ode ti iwe-irohin *Daily Times* sọpe awọn gbọ pe o salọ kuro ni Ijebu-Ode nitori esun kan ti agbọ pe nwọn nfi sun, wa si ọdọ Lọya pataki kan ni ilẹ yi, a si gbọ pe Lọya na ni ki o pada lọ si ilu rẹ.

## DUNIYAN—LABARI.

[ LATI ỌWỌ KEKERE-AWO. ]

ẸGBẸ ṢỌṢI BẸTẸLI.

Awọn Ẹgbẹ yi ṣe ere pataki kan ni ile ẹgbẹ Ẹhingbẹti *Glover Memorial Hall*, ni alẹ ọjọ Alaruba ni abẹ alaga Ọlọla Lọya T. Adebayọ Doherty, ati awọn jasanjakan—gẹg bi iwe akiyesi.

SAKARA ABINKAREWA.

Anu ṣe ni lọpọlọpọ l ti mi gburo ijo aitọ ti awọn ọmọge miran ma mba awọn okunrin jo nidi sakara ti nwọn njo, ki irufẹ awọn ọmoge alai lojuti baun lọ ronu wo diradira, bi nwon ko ba ri ẹni kilọ fun wọn, gbogbo rẹ lo nlọ bi o ti nlọ yi iwa jagbajagba ọmọ Anabi Adamu lo tunbọ ṣe okunfa rẹ.

ỌMỌ EKO NDABIRA.

A sọ ti awọn ọmọ wundia tabi ti adelebọ aṣa miran nro lati ti ọdun melo sẹhin ko darara ara, nwọn nro aṣọ si kọja ẹrunkun, omiran fẹrẹ le ro

de itan ti nwọn ba nlọ lode. Nigbati a wadi iru aṣa bayi, a gbọ wipe nwon ni ẹniti ko ba ro irufẹ aṣọ bẹ, ko gbajumọ tc, tabi ara oko li o nṣe, awọn ọmọ Imale ni a kọko ṣe akiyesi iru aṣọ bayi lọdọ wọn, ṣugbọn ni isisiyi o ti di ti ọp lọpọ enia ju gbogbo rẹ lọ aibẹru Ọlọrun to lo mbẹ fun irufẹ awọn bẹ, ṣugbọn o yẹ ki a mọ wipe irufẹ aṣa palapala bayi lo nfa musiba Ọlọrun wa—mẹlọ-mẹlọ dọwọ iyin o !

### AWA-MOTO.

A tun bẹ awọn owiwa miran ni ọsẹ yi ti nwọn ma nsaba wa mọto bọ lai ki nfun ara won ni aye to lati kọja nigbati nwọn ba nkun bọ bi ojo. nipa eyi o ma njẹki nwọn ma njamu arawọn ti nwọn ba mbọ.

### LEMỌMU ILU.

Ni ọla ọsẹ ti o nṣe ọjọ kokanla oṣu yi ni yio di ọdun marun gbako ti awọn Jamat Musulumi-ilu fi Mọmọdu Ligali jẹ oye Lemọmu-agba. Nwọn fi Ligali jẹ Lemọmu si Mọṣalaṣi Jimọ *The (Ceutral Mosque)* ni ọjọ kokanla oṣu *November*, *1923*, ọjọ *Sunday* bi ọla yi larin iho ayo ati inudidun. ilu dun diẹ nigbana, owo mbẹ, alafia mbẹ, aisan kosi ni ilu bayi yungba ni gbogbo rẹ ri.

Ni ọsẹ ti o mbọ lagbara Sati a o yin diẹ si nyin leti ninu awọn wosika, gẹgẹbi a ti ṣe akiyesi iṣẹ si lati ọdun karun na titi di oni, a tọrọ ọpọlọpọ alafia ati ẹmi gigun fun u, ki Ọlọrun jẹki o le tẹ awọn ọmọ ẹhin rẹ lọrun kalẹ, bẹni a si ṣe adura fun awọn isangbe rẹ na, ki ajinde ara ma jẹ fun wọn—amin.

### ỌJỌ NRE 'BI ANA.

Ni ọjọ kẹrinla oṣu yi, ti o ku ireni yi ni Ọgbẹni Herbert Macaulay yio di ẹni ọdun mẹrinlelọgọta, a ti ṣe wosika pataki n'pa ọjọ ibi rẹ ni ọdun to kọja, nitorina fi eyi si ọjọ miran ọjọ 're. Ajinde ara ki o ma jẹ fun u—amin.

### AWỌN FILANI ATI ẸSIN MUSULUMI.

Ni oni a ṣe ẹda ọrọ Ọgbẹni A. L. Hethersetl ti a ri ka ninu iwe yoruba kan ninu wosika wa nipa itan iṣẹdalẹ awọn Filani, bi awọn Filani tiṣe di Imale, ohun ti o mu ki awọn Filani bẹrẹ si ogun jija ati iṣẹgun awọn Filani—A ṣe iranti eyi fun anfani awọn Musulumi miran ti ko ni iwe ti a wi yi lọwọ.

---

In honour of his 35th Birthday falling on the 3rd instant Mr. W. W. Beecroft of 6, Simpson Street, Lagos, was "At Home" to a few friends in the evening of the same day.


## KERE O!

OYINBO KESSLER GBE TANA DANU, O GBE KI DE.

Irin-iṣẹ Gbẹna-gbẹna to dara ju ti nwọn ti nlo fun iwọn adọta ọdun sẹhin wa fun tita ni Ṣọbu **Kessler.**







Ẹ ba mi lọ si Ṣabu na, ẹ o ri ti nyin yan nibẹ, ọpọku ọyọku ni owo rẹ, iba diẹ ni o wa. Aworan Irin-iṣẹ wọnyi ni a ya sinu iwe yi fun nyin yi. Lọgan lẹ o ri ra.

Ẹ lọ yan ti nyin ni Ṣabu Oyinbo KESSLER ni No. 7, Labinjo Lane, ni Eko.







Ẹnyin ara Eko,, ara Oke ati ilu miran, gbangba dẹkun, kedere bẹwo, Ṣabu Kessler ti kuro ni mori nkan firi irohin ko to afojuba. Ẹ ma ṣe gbẹhin ki ẹ to ra ti nyin, ki ẹ ma ba joku Ologbo.

## "IKU DORO."

Anu şe wa pupọ lati ri iku omọ iya meji o ni arin ijọ mẹta si ara wọn, iyẹn Ellen Caroline Oluyẹmi Taiwo Adegun ( Nee Bright ) ati aburo rẹ ọkunrin Ezekiel Ẹbun Akiwande ọmọ bi ọdun mokanlelogun—Ọlọrun ki o gbe wọn si afẹfẹ rere, ki o si pa aşişe wọn rẹ. A si ba iya wọn kẹdun ki o fi gbogbo ọran rẹ le Ọlọrun lọwọ. Tanimọwo, Ọlọrun lo fi wọn fun ọ, Ọlọrun na lo si gba wọn lọ, ibukun ni fun oruko Oluwa, a ba awọn ẹbi Bright kẹdun ati awọn ẹbi Adegun, Ọlọrun yio tu nyin ninu—amin.

A si tun daro iku ọdọmọkunrin ti a npe ni Akande ti ode Onde, to ti wa si Eko ni iwọn ọdun meji sẹhin to si ku ni arin meji awọn ara wọn yi ni Eko—ki Ọlọrun ko tu awọn ẹbi rẹ ninu—amin.

A si ki Mrs. Charlotte Olufisayọ Mousali ( Nee Bright ) ẹniti o de pẹlu ọkọ Kabọ nipa iku ẹgbọn ati aburo rẹ ni ọjọ *Thursday*. Ọlọrun yio tu ẹ ninu. A ko si tun ni ri esiko yi—a mọ-mọ o.

A tun ki Ọgbẹni Albert Edward Elud lapọ Bright ẹniti o ti fi Eko silẹ ni ọdun bi marun silẹ lọ si ilu Hausa to si jẹ Akọwe agba fun awọn oyinbo Mongu ( N ) Tin Mines ni Jos kabọ ni ojọ Thursday ọsẹ yi fun isimi to gba wa sile, a si ki ẹgbọn J. Adolphus Bright o ku atojuba ati gbogbo ẹbi patapata—Albert kabọ o.

## ỌRỌ ELEKO KO RI BẸ.

"Bi aba gbagbe ọrọ ana, ako ni ri ẹni ba şere" Ọrọ oke iwe yi lo wa si ẹnu wa, nigbati a ba niran asiko ti rog odiyan nipa Ọba wa Eshugbayi Eleko ti bẹrẹ lati bi ọdun kẹsan sẹhin wipe wọn ni lati yọ, ti awọn ẹgbẹ ilu dide si ọrọ na, ti Gomina ati Ikọba keji rẹ ati Resident of the Colony fi joko pẹlu awọn mẹtala lati ji roro wipe ba wo ni wọn ti ma şe ọrọ na si lati yọ, ti Gomina si pe awọn mẹtala gẹgẹ bi awọn oni mọran wipe ewo ni wọn ri si, ti awọn mẹtala yi fi tako awọn mọkanla, a le bere wipe awọn wo ni awọn mẹtala ijohun awọn yẹn ni wọn yi:—Bishop I. Oluwole, Hon ( now Sir ) Kitoye Ajasa, Hon S. H. Pearse, Hon Eric O. Moore, Dokita Randle, A. Savage, Obasa, awọn Ọgbẹni David Taylor, Akşemọyin, J. K. Coker, James George, Moronfolu Abayomi ati alufa kan iyẹn ni oni we ti akọ ọrọ yi ninu rẹ ro wipe T. A. J. Ogunbiyi ipade yi şẹlẹ ni ọdun 1919 ijọ kejila oşu November 1919 ninu awọn ẹni mẹtala wọn yi, meji ninu wọn ti di ẹni igbala awọn yẹn ni Dokita Randle gbogbo enia lo ni ran ijo to ku ati ẹyẹ ti awọn ọmọ rẹ şe fun ni ọjọ na—ẹni keji ni Lọya Moronfolu Abayomi gbogbo wa ni yio şe iranti agba ko iku to ku lati ọwọ Delphonso iyẹn papa ko ma mu aiye ra, şugbọn kini oyẹ ki ama şe oju isaju enia, nitori ẹyin ọla, wipe ni jọ kan lawa oşa lo, ti ao jihin gbogbo işẹ wa laiye fun Ọba ọrun ti ko ni şe Ọba aiye mọ, nijọ na ni gbogbo wa la o ma jihin fun Baba.

Ninu ipade ti ijọkẹtadinlogun oşu November 1919 ti gbogbo ilu pe sẹ bamu-bamu ti wọn si jẹ ẹgbata enia lọ ni Ilupesi ti ologbe Lọya Shyngle si wa nibẹ gẹgẹ bi alaga, ti gbogbo enia nsọrọ nibẹ şugbọn eyi ti mo fẹ fi han ninu gbogbo ọrọ na ni ti Ọgbẹni wa Lọya Adeyẹmọ Alakija, ki nto lọ ohun to sọ mofẹ kẹ gbọ ohun ti Timothy wi ninu bibeli "şugbọn iwa-b-Ọlọrun pẹlu itẹlọrun ere nla ni; nitori awa ko mu ohun kan wa si aiye, osi dani loju pe awa ki yio si le mu ohun kan ti inu rẹ jade."

Ọrọ ọgbẹniwa yi lọ ba yi pe ni Ede oyinbo.

BARRISTER A. ALAKIJA :—Chairman and gentlemen, there are several speakers who I understand, are going to speak to you in English and I have been asked to speak in Yoruba, as for me I can speak both in English and Yoruba. We have heard that some collection is being made and is about to be utilised for a petition on behalf of Prince Eleko. those who have paid anything showed please hold up their hands.( No show of hands. ) I say that the 13 are not able to speak for the country, because the educated classes are not all invited. Take it religiously how many Wesleyans were there, how many Roman Catholics, Baptist, Mehommedans and Pagans? None! Here is the Leader of the Bar of Nigeria before us, wherever he is not invited to, the Bar is not represented, same can be said of our Doctors, I say it at this meeting, and I can say it anywhere that the 13 is not the Community. The next step we showed beg the Governor. I, in my own opinion, see nothing of which Prince Eleko is guilty to warrant his proposed deposition.

Ẹyin ara mi ọrọ ti ọgbẹni wa Lọya Adeyẹmọ Alakija sọ ni ijọ na re lori ọrọ Ọba wa kan na to wa ni Ọyọ loni re, eyi fi han wa gbangba wipe ni asiko na, gbogbo awọn Ilu wọn ni Otọ ni ẹnu ko si si agbọ teku wi fun ẹyẹ ninu wọn otitọ ni wọn fi mu ẹgbẹ na duro ninu ẹgbẹ kan na yi, ni wọn ti da Dẹmọ silẹ. Njẹ mo bere I wọ yin ninu awọn ẹgbẹ Igbimọ ilu igbana, awọn da loni yi, igbi aiye ti gbe won lọ, a ko si ri wọn ninu ọrọ ilu şugbọn ẹgbọ bi Mattew ti wi"

"Ẹjẹ ki imọlẹ nyin ki o mọlẹ tobẹ niwaju
"enia, ki nwọn ki o le ma ri işẹ rere yin, ki
"wọn si le ma yin Baba nyin ti nbẹ li ọrun
"logo"

Ọrọ Ọba wa yi Prince Eshugbayi Eleko Ọbangiji Ọba Ogo yio jẹ ko yọri si rere—Ile la boye. nbọ si—Adun lo kẹ hin ewuro.

..kan to ba jọ ara wọn la fi nwe ara wọn, awọn agba lo ma npa lowe wipe " epo ẹpa jọ posi ẹlẹri " on ni ọro ti a ri ka ninu iwe irohin to sọ wipe ( *twenty-four years ago* ) ọdun mẹrinlelogun sẹhin, wipe ni agbala ibi ti nwọn gbe nkọ iṣẹ Lọya ki Oluwa rẹ to wa di Lọya, awọn ti nwọn yege ninu ofin Romans ni wọnyi : Moronfolu Abayọmi ( iyẹn ti di ero ọrun loni, ki Ọlorun ko dẹlẹ fun, ) M. N. B. Wilson iyẹn ni Lọya wa ti ita Balogun ni Eko ọgbẹni wa jẹ ẹlerin ẹyẹ, o si feran awọn ọmọde pupọ, nipa iwa enia, Ọgbẹni yi jẹ ẹniti o ni iwa pupọ, awọn ti nwọn yege ninu ofin iṣelu ( *Constitutional Law and Legal History* ) F. M. Baddeley ọgbẹni yi jẹ Oyinbo on ni ẹniti o gba ipo Cameron, Sẹkitẹri Ọba o si jẹ adele Gomina wa Graeme Thompson ni ode Eko loni yi, ẹnikeji ni Donald Kingdon, ẹniti o jẹ olotu ofin Attorney General on lo si gba ipo igbakeji Sẹkitẹri, H. M. M. Moore ẹniti o fi ilẹ yi silẹ lọ si ilu miran baun-baun, ẹnikẹta ni P. B. Petrides ẹniti o jẹ ikan ninu awọn adajọ wa ni kotu nla ṣugbọn o wa ni Calabar loni, o lọ gba ipo adajọ Webber enikẹrin ni W. A. Savage ninu ofin ẹri ati ninu muni-muni ( *evidence.* )

Procedure and Criminal: Ọgbẹni wa J. T. N. Cole ti ẹhinkule Shitta ati adajọ P. B. Petrides ẹniti o ko iṣẹ tan lasiko na ni on ni kan ni E. J. Alex Taylor ẹniti o jẹ okan ninu awọn ogunna gbongbo ninu awọn Lọya ti a ni loni ni gbogbo ẹkun Najeria. Ohun to mu wa lati tu mọ gbogbo nkan wọnyi on ni wipe ataku imado, bi a ti wa ri ni aiye bẹni a o ri gẹgẹ bi wọn ti ma nsọ wipe akunlẹ yan ni a de aiye ba, ki okan ninu awọn Lọya wa fi oju di ẹnikẹni ninu awọn oyinbo mẹta yi, yio kan abuku, bi wọn si fi oju wipe bayi ni aṣe mọ ara wa, ibi kan na ni a ti kọ iṣẹ, mo tilẹ gbe ninu idanwo, aroye ọtẹ ni tẹtẹ yio jẹ oluwarẹ, a si dupẹ lọwọ Baba wipe awon Loya ti wa wọnyi, nwon si nṣe iṣe wọn, ko si si alebu kan ni ara wọn lati ọdun mẹrinlelogun yi wa iyẹn to ayọ fun wa.

---

Ọrọ wa ti osẹ yi, ọro kan la ma fi jẹ omitoro ekeji, nitori bi a ba fi ọwọ wẹ ọwọ on ni ọwọ fi nmọ, ko si ẹniti kole ri iriri aiye, gbogbo nkan to wu ki enia le ni ni aiye yi, ko ma rope kole tan, bo jẹ ogun to nfi iyẹn yan ran, ohun to ntan ni egun ọdun, ọmọ alagba ni lati ra akara. nwon fun ẹ ni ile o nkun ni ẹfun, o gbọn to ẹni to kọ ile silẹ, awọn alaṣiko ni wọn ma nkọ lorin wipe " ki lori to nyanran " ọpọlọpọ awọn ẹniti wọn ni ile ti wọn kan asẹ ni won ti di alahoro loni Ọlọrun ki o ma ṣe wa bẹ, ni ilu oyinbo papa awọn ẹniti nwon jẹ olowo *millioneer* won di ẹniti kọbọ kan ma nwọn, gbogbo rẹ ka aiye, ẹniti o ti nṣi ṣọbu janrẹrẹ ri ti di ẹniti nwon ngba si iṣẹ akọwe, bẹni a ba aiye, ọpọlọpọ ifẹkufẹ obinrin lo mu owo won, Ọlọrun ko ṣọ wa ninu rẹ, ọpọlọpọ iṣubu ọmọ alakeji wọn ni nwọn nwo, awọn papa ti di ẹni igbagbe, aṣa awọn yoruba, nwon aki yago fun ẹlẹsin eṣi, bẹbẹ kari aiye.

Mo ri ka ninu iwe irohin kan wipe Ọgbẹni Alfred P. Da Costa pe J. P. Dawodu ni ẹjọ fun £163, owo irin ẹsẹ £5 : 3 : o adajọ Tew nigbati Lọya Wilson ko ọrọ balẹ nipa Ọgbẹni Dawodu wipe o ti jẹ ẹniti ẹgbẹrun pọnwun ko pa ni idi da ṣugbọn loni ti o jẹ wipe gbese lokun ọrun rẹ nigbati adajọ ro ọrọ na wo tan, oni ki Ọgbẹni Dawodu ma san ṣile kankan ni oṣoṣu, o ni on palaṣẹ, ki Ọgbẹni Dawodu ma ṣe gbagbe wipe on jẹ owo yi, ṣugbọn ki ni a ma wa irufẹ eyi on nipe ki Ọlọrun ṣe ayipada anfani, a si ni lati ki adajọ Tew pe o ku lakaye a si ki Lọya Wilson o ku iṣẹ.

Ẹnyin enia wa, ọrọ wa de ibi ti asopa gbengbe ọbọ ṣe wọn ni asopa ko le palamọ nu ṣugbọn ọrọ wa de ibi ti a gbe ma sọ otọ ọrọ, ọrọ yi ni ẹjọ ti Abu Bakare Kẹhinde, Amọdu Tijani Oyeto ati Amọdu Rufai Oyewọle pe Adamọ Akẹju (Chief Ọbanikoro ) Jọsẹ Ogunfunmi ( Chief Onitana ) ati Yesufu Omidiji—ẹ wa gọọ idajọ Ọgbẹni Berkeley adajọ kotu nla bi o ti sọ.

" O ni eyi ni ẹjọ ti awọn to pe ẹjọ fun atọjudi ti wọn fẹ gba owo fun iwa aitọ awọn ẹni wọnyi si wọn. Gbogbo awọn ẹniti wọn pe ẹjọ ati awọn ẹniti wọn pe jẹ ẹgbẹ ile oṣugbo. Awọn ti won pe ẹjọ jẹ awọn ẹbi Eletu Ijẹbu nwọn si ni ile ni Great Bridge Street ni Eko ti wọn si ni iwe ile na ni ọwọ, ninu ile yi ni ile ọgbẹni gbe wa, ni ọjọ kọkandinlọgbọn oṣu *December* 1926, ( awọn ti nwọn pe ni ẹjọ wa si agbo ile Eletu Ijẹbu ni Great Bridge Street, nwọn si wọ inu rẹ, awọn ti wọn si jẹ ẹgbẹ ogbẹni si wọn wa, nwọn si wọ ile lalai gba aṣẹ lowọ awọn ẹbi Eletu Ijẹbu. Nwọn si lọ si ibi ti ile Oṣugbo gbe wa, ilẹkun ibẹ si wa ni titi, wọn si wọle nipa fi fi ipa mu nkan ti wọn fi ti kuro, wọn si fi ohun titi ti wọn sibẹ dipo eyiti o ti wa nibẹ ri, wọn si mu kọkọrọ lo, ni ọna keji ẹwẹ, nwọn wọn ile Oṣugbo nipa fi fi agbara ṣi ilẹkun na, eyti o jẹ ohun pataki ti nwọn pe ẹjọ si awọn ti nwọn pe ẹjọ wọn ni ile Oṣugbo yi ti awọn Eletu Ijẹbu ni, ati pe awọn ni wọn ni ile ti ọsa yi wa nitoripe awọn ni won ni wọn kọ, ati pe ko si ẹniti o ni lati ṣi fun etutu lalai jẹ afijiku jẹri to ba ohun ti a wi yi mu. O si sọ pe gbogbo ẹgbẹ lodi owo ti nwọn fi kọ ile Oṣugbo yi.

Ẹjọ ti awọn ẹnikeji ni pe, ile Oṣugbo ti gbogbo wọn ni. gbogbo wọn ni wọn ni ẹtọ si ni asiko ka-siko lati ṣe ohun pataki to ba ya, ṣugbọn eyi ni awọn ẹniti o pe ẹjọ ni wọn ko le ṣe, nipa eyi ni awọn ti wọn pe ni ẹjọ fi lo agbara won lati le mu ti wọn ṣe wipe gbogbo ẹgbẹ Oṣugbo loni si loju ti on nkan lasan ni eyi ti wọn nja le lori, wipe nkan to je nkan aṣiri ti inu kan na ti gbogbo wọn mọ ni. Ki a wo gbogbo rẹ wo ko to ohun ti wọn

ma ja le lori, ni gasikia ija yi jẹ ọkan ti ko mu ọgbọn dani rara. Awọn Oṣogbo wọnyi ti pin si meji larin awọn awo tọtun ati tosi, awọn apakan wọn ko erupẹ fun Eleko Akitoye awọn apakeji tẹle ẹniti on gba ipo rẹ Eṣugbayi Eleko ti nwọn mu lọ, fun ẹri ti o wa niwaju mi, ko si iyemeji wipe nkan wonyi lo dı nkan yi si, awọn ẹniti wọn pe ni ẹjọ nwọn nfẹ aye lati lọ si ile Oṣogbo wipe ki Oba to ṣẹṣẹ jẹ le lọ ṣe etutu to ni lati ṣe gẹgẹ bi ọmọ ẹgbẹ yi, awon to pe ẹjọ ẹwẹ fi akeke kọri wipe won ko ni ṣe nkan nibẹ. Awọn ti won pe ni ẹjọ nwọn ranṣẹ si apeni ko lo ṣi ile Oṣogbo silẹ fun won lati ṣe ohun ti won fẹ. Ṣugbọn esi ti nwọn gbọ nipe ko ṣeṣe nipa bẹ nwọn lọ sibẹ lga Eletu Ijẹbu pẹlu ipa wọn si fi ipa ṣi.

Emi kọ irufẹ ọna ti wọn gba yi nipa mimu ileri wọn ṣẹ, iwa bẹ o fa ibinu ọmọ enia ṣugbọn fun Ọlọpa meji to duro to ba wọn wa, bi bẹkọ yio di ohun to ma ba alafia ilu jẹ, lọna keji mo ri pe o jẹ iṣoro wipe iwa ti awọn a a ibi yi hu to on to le mu ẹjọ dani. Emi ri daju pe ile ogboni jẹ ile gbogbo ẹgbẹ patapata ti wọn le ma lo bakanna, bi asiko ti aiyan jiyan ba de ko si eyiti ko ni ẹtọ ninu apa kini ati apa keji. Nipa pe wọn fi aitọ wọ ile Eletu Ijẹbu wọn nt ẹto lati wọ lọ tabi wọ jade ati ile oṣugbo ati pe ko si ẹri iyẹn niwaju mi pe wọn lọ tabi jade nibiti wọn ni ẹtọ ati gba, Ẹjọ ti wọn pe yi ṣubu. Nitori mo fun awọn ẹniti wọn pe ni ẹjọ ni idajọ. Ṣugbọn lati fi han wipe mo kọ irufẹ iwa ti awọn ti wọn pe ni ẹjọ hu, nipa fifi agbara se lori ẹtọ won, emi sọ pe ki awọn mejeji san owo irin ẹsẹ fun ara wọn.—(Sdg) H. S. Berkeley. Mo tun mọ idajọ yi lati inu iwe irohin Daily Telegraph mo juba olotu iwe irohin yi. Ẹyin enia wa, ẹ wa ri oju ẹjọ lode wa yi, ẹwa sọ-fun mi wipe ida ọ wo ni enia le fi ọgbọn da ju eyi lọ. Ni temi emi gba fun Adajọ Berkeley o lo ẹtọ osi sor to jina hanhan lai fi ṣe oju saju, oni ki olukuluku fi ọwọ mu iye to na. Osi da awọn ti wọn pe ni ẹjọ ni are. Gbogbo ara ilu, ẹwa ri irufẹ enia ti Adamọ Akẹju jẹ wa yi, to nmu ofin dani lati ọwọ ara rẹ, to si nlo bo ti fẹ, bẹ lo sọ nigba ẹjọ ti ẹtu wipe ati oku ati aye Eleko on ko lẹ ti, ninu ẹjọ yi papa oni on ko jẹ lọ si ṣabu ọlọpa ayafi ọdọ Aṣoju, ibẹ lo ti gba ọlọpa lati la fọ ile onile iyẹn ni ile Oṣugbo ti Eletu-Ijẹbu gbogbo nkan wonyi wa jẹ iwa to to ninu ilu ofin ilu Gẹsi ki ẹnikan ṣa ko ma ni gbogbo nkan afi ti on ṣa ni, ẹniti otun sọ ninu ibura wipe on ko lọ si ile Oṣugbo iwọ nigbati Eshugbayi ti ko werewere rẹ de, njẹ mo bere ki ha ṣe Eshugbayi na lo de fila ori rẹ fun? Ka tun pada ka mi fi ibi ṣi olore, ẹ gbọ bi oni Psalm ti wi:—Ọlọrun mu ẹni ofo joko ninu ile, omu awọn ẹniti ade ninu ẹwọn jade wa si irọra: ṣugbọn awọn ọlọtẹ ni ngbe inu ilẹ gbigbẹ."

Emi ni ti nyin nitotọ,

ENIA KO DA BI ALLAH.

## DIẸ NINU IṢẸ IYANU ILẸ WA.

### ABIKU TABI ELERE.

Mo kiyesi aṣa kan pe nigbati enia ba bimọ-ku, ọpọ awọn alaimoye ni isọ ẹjọ di ẹjọ ọmọ titun to ṣe alaisi. A ha nṣe bẹ ninu ohun miran bi? Bi Agutan tabi ewurẹ kan ba nbimọ loṣu meje-meje, bi adiẹ kan ba nfi ẹyin kan pa mẹji, gbogbo enia a ma sare lati ni ninu ohun osin bẹ; ṣugbọn aguntan tabi ewurẹ ti nṣenu, tabi ti ọmọ rẹ ki dagba, adiẹ ti ọmọ rẹ nrẹ danu, tabi ti nfi ẹyin mẹjọ pa ọmọ mẹta, pẹpẹiyẹ ti ki tọ mẹji dagba ninu ọmọ merin-dilogun, ẹjọ ti tani? Ẹjọ ti awọn ọmọ ni tabi ti obi? Kaka ki a lọ gba Oriṣa Elere fun awọn ohun ọsin wọnni ki nwọn ba le bimọ-la, tita kọ ni a nta wọn? Nigbati o gbin igi eleso sinu ọgba, omiran ko ha wa ti idaji eso rẹ nrẹ danu ki awọn ti yio pọn to ma pọn? Ẹjọ eso ni tabi ti igi? Bẹ gẹgẹ ni nipa ti enia.

Abiku ki iṣe ẹjọ ọmọ kikoṣe ẹjọ awọn obi. Aṣa buburu kan wa larin awọn enia ilẹ yi pe, nigbati nwọn ba wipe nwọn lọ tu ẹniti o bimọ-ku ninu, nwọn a ma bu ọmọ to ku bi ẹnipe ẹni ọmọ na wa lọwọ ara rẹ, bi ẹnipe on lo fi ara rẹ fun iya rẹ, on lo si gba ara rẹ lọ, ika li eyi, ko si dara. Tani obi na to le ranti iru ijakadi ti ọmọ on ja titi o fi de oju iku, ti i iru irora ti a ko le fi ẹnu sọ ti ọmọ na ke: Obi wo lo le ranti iwo anu ati ikerora ọmọ rẹ to ku, ki okan rẹ gba a ki a ma bu ọmọ na lori gbogbo rẹ! Si ẹsibẹ iru ika yi ni ọpọ ko bẹru lati ma ṣe nigbati nwọn ba lọ sile ọfọ. Nipa iru iwa bayi ọpọlọpọ obi li a ti fi agbara mu lati din ifẹ wọn ku si ara ọmọ won, ati lati ma wo wọn bi ọdaju ati alailere ọmọ. Ọpọ la si ti mu lati ma ṣe ajo ainidi fun ọmọ tobẹ ti nwọn fi sọ ara wọn di ẹru awọn ọmọ bẹ.

Nipo eyi, o yẹ ki awọn obi ti nbi abiku toju iru arun to wa lara wọn, ti nwọn si nbi pẹlu ọmọ wọn. Arun ni abiku! otitọ nla li eyi, o si ṣoro lati gbagbọ lọwọ awọn ti kan wọn ti ri si ifọju ibọriṣa. Ṣugbọn a ko le ṣai sọ otitọ pe, ko si abiku tabi elere nibikan bikoṣe ninu arun. Ki iṣe ẹjẹ gbogbo ọkunrin ati obinrin lo le dapọ lati bi ọmọ onilera. Ẹwẹ, ka mu iyipada ti nwonu ẹjẹ nipa iṣẹkuṣe kuro, ko si ẹjẹ ẹnikan to ri bakanna ni gbogbo ọdun aiye rẹ, bi ọjọ wa ti nlọ, bẹni gbogbo ohun elo inu ara wa nyipada, ti o si ndinku ni ipa ati agbara.

Ọpọ ọkunrin ati obinrin ni ima ro pe arun ko si lara won nitori awọn bimọ. Iṣina nla li eyi pẹlu. Ọpọ arun lo wa ti ki jẹ ki enia le bimọ rara, ọpọ lo si wa ti ki idina ọmọ, ṣugbọn ti a nbi mọ ọmọ, ti o si le ṣe iku pa iru awọn ọmọ ti a fi arun bẹ bi. Ninu iru arun bẹ ni awọn arun meji bi mẹta ti nsọ abiamọ di alabiku nipa aikiyesi ara li akoko wa.

*Iwe-irohin Eko.*

**EKO AKETE**

EKO, SATURDAY, NOVEMBER 10, 1928.

## ETUTU KOSI EKO D'OKU.

Lati ọjọ ti Alaiye ti d'aiye ni enia ti mọ ohun ribiribi ti etutu ṣiṣe jẹ. Oyinbo mọ̄ Enia Dudu mọ̄ Enia alawọ pupa bi aṣọ ododo mọ̄: bi ẹnikan bimọ ti o si ko ọmọ na jade, o ni oriṣi etutu idile rẹ ti o ma ṣe nigbati nwọn ba nko ọmọ na jade: Oyinbo miran atilẹ wulẹwulẹ se ase rẹpẹtẹ ti a ti a npe ni *Dinna* eyiti yio pe awọn ẹniti o ba fẹ si: ti a ba bi Oyinbo yi ni eredi irufẹ onjẹ bayi; yio ri sọ fun awọn ti o ba jẹ ọrẹ korikosun rẹ: Imale mọ riri etutu nipa sara ti nwọn ma digba ṣe lẹkọkan: Kiriyo si mọ pẹlu nipa fi fi owo ṣọwọ si Ṣọṣi wọn fun nkan ribiribi ti Baba Afunni-masiregun ti ṣe fun wọn awo yi jẹ etutu ni ọna tirẹ: melomelo ni a tun le sọ pe kosi ilu ti ko ni etutu tirẹ.

Ni igba lailai enia ko ni ti ṣi ẹsẹ bi meji mẹta kan ki oluwarẹ to ri ẹbọ rẹpẹtẹ ti awọn kan ti fi oru boju gbe lọ si ita gbangba: pupọ ninu wa si le ṣe iranti irufẹ orin ti awọn ọmọde igbani ma nsaba kọ kete ti nwọn ba ti ri irufẹ ẹbọ bẹ ni ọna ibiti nwọn ngba "Ẹbọ Ẹlẹbọ pada lẹhin mi" jẹ orin ti awọn ọmọde ma nkọ ni akoko bayi; etutu dabi igbati enia bu omi tutu si ara ni arọ ni akoko oru ti ara yio tu oluwarẹ wọ̄wọ̄ gẹgẹ bi a ti mọ ohun pataki ti etutu ṣiṣe jẹ njẹ a le sọpe ilu Eko wa yi tun ni etutu kọkan ninu mọ bi ti igba lailai: ki a ma tan ara wa jẹ kosi etutu kan mọ ni ọna ti iṣẹdalẹ wa sisiyi: nigbati Ọtẹ koi ti si ti Eleko mbẹ nipo rẹ a mọ iṣẹ nlanlan ti o nṣe nipa ṣiṣe etutu si igboro Eko ki ilu ki o le tù ki o le bà: kosi si igba ti o le ma ṣe etutu yi ti owo ati òwò (trade) ki ngberi si ni arin wa l' Eko nibi: aisi irufẹ etutu yi lo mu ki gbogbo nkan ma lé koko bi oju ẹja ni ode oni: ọmọde nke àgbà nke ọkọnrin nke, obinrin nke, gbogbo rẹ di tiratira: ẹnyin ẹ tun wo arun ti o bẹ silẹ yi bi igbati Obẹle kija mọlẹ lati ọdun diẹ sehin yi wa etutu melo ni a ṣe si? Rogbodiyan wiwa Eleko lọ ko ti pa pupọ nkan loku bi nkan etutu melo lo mbẹ ni Iga lode oni? lasan ni awọn ẹlomiran le ma sọpe ẹniti ẹniti o wa nibẹ nṣe ibẹ ṣugbọn jijọ lo jẹ oṣupa ko le j'ọsan: Ilu nfẹ etutu lọpọlọpọ ki gbogbo nkan ti o le kankan yi le rọ:

O yẹ ki Ijọba ba ni ri si ọran yi ki nwọn si mọ pe wiwa Eleko lọ jẹ nkan ti o pa owo l'oku ati lilọ siwaju òwò: a sọ eyi ni ọsẹ tokọja: Eko ha le ma wa bayi lọ titi lai si etutu kọkan ti a o ṣesi njẹ ninu ki awọn kan ma wọ mọto kiri ilu ki nwọn si ma fi ara wọn han pe awọn ko ku ni Ilu ma joko ti?

Eko nf' Etutu! Eko nf' Etutu!!
Eko nf' Etutu!!!

---

## YOUNGMEN XTIAN GUILD.

Ni ọjọ ọsẹ ti o kọja yi ni awọn Ẹgbẹ ti a da oruko wọn yi ṣe ajọdun kini, lati igbati nwọn ti da Ẹgbẹ na silẹ ninu Ijọ Bethel ti Eko, a gba fun awọn ẹgbẹ na fun alafia, ayọ ati iyẹsi ti wọn fi ṣe ajọdun na, a si ṣe isin pataki fun ẹgbẹ na eyi ti o wu ọpọlọpọ ena lori. Rev. Abọyade-Cole ni ẹniti o ṣe iwasu ni alẹ ọjọ na, ṣugbọn ohun ti o fẹrẹ da bi ẹnipe o ku diẹ ki o to, fun isin alẹ ọjọ yi ni ti orin eyi ti o jẹ wipe a ko ni ero tẹlẹ ti o ya wa ba wa ni eburubu, nitoripe ọtọ ni orin eyiti atẹ-duru wa fi ọkan si lati ba tẹ fun awọn ijọ, ṣugbọn omiran ti ko ni reti li a fi si waju rẹ, eyi si ni kọkọrọ ti o fẹ ba ẹhin aja jẹ. Iba dara lọpọlọpọ bi o ba jẹ wipe ohunkohun ti nwọn ba fẹ ṣe nipa ti orin ninu Church jẹ mimọ fun awọn atẹ-duru, ṣugbọn ẹja ti o rekọja si ibu kọ ni a tun ndẹ igere de o, bikoṣe omiran ti o tun mbọ wa.

Orukọ awọn mẹmba ni wọnyi:—Ọgbẹni W. A. Dawodu, Baba isalẹ, Ọgbẹni J. H. G. Willoughby, Baba-ẹgbẹ, Ọgbẹni J. M. Ṣonubi, igbakeji Baba ẹgbẹ, Ọgbẹni G. I. Vicent, Ọgboni Oke Adeṣigbin, Madam Araba Taylor, Iya-ẹgbẹ, Ọgbẹni Henry Willoughby, Atẹ-duru, ati alatunṣe awọn ọmọ ẹgbẹ na. Awọn arakunrin A. A. Ẹnlọh alaga ẹgbẹ, O. A Ceker, akọwe, ẹgbẹ, A. Oloyede, ibikeji, M. A. S. Abọn, olutọju owo ẹgbẹ, A. Ọlaiya, ibikeji rẹ, awọn ọmọ ẹgbẹ: E. O. Daniel, O. M. Coker, S. P. Coker, D, O. Martins, G. M. Ogunkanmi, A. O. Vicent, A. Onitiri, A. George, N. S. Adeniji, E. O. Ladeinde, J. A. Beckley, J. O. Abiọla, M. A. Lukan, D. Akinlade, J. A. Thompson, Victor

Akinọla, Victor Willoughby, J. O. Olowu J. O. Kukọi, S. A. Cole, J. O. Otuyẹlu.

Bayi ni orukọ awọn ara wa na lọ—aṣe yi ṣe ẹmi ajinde ara yio ma jẹ fun gbogbo nyin patapata.

## Olusakin's Column.

CONGRATULATION.

Mr. E. A. Bright, Head Account's Clerk, Locomotive Department, Ebute-Metta, has been promoted Assistant Chief Clerk.

Mr. Bright is a younger brother of Mr. D. A. Bright, of the Railway Press.

*( From the Nigerian Daily Times ).*

TWENTY-FOUR YEARS AGO.

Turning over the pages of the London *Times* of November 2nd, 1904, we came across the following announcements under the Council of Legal Education.

AWARDS OF THE COUNCIL.

Roman Law :—Moronfolu Abayomi ( deceased ), M. N. B. Wilson.

Constitutional Law and Legal History :—F. M. Baddeley, D. Kingdon, P. B. Petrides, W. A. Savage.

Evidence, Procedure and Criminal Law :—J. T. N. Cole, P. B. Petrides.

Final :—E. J. A. Taylor.

INTERESTING COURT DECISION.

**£168 to be paid by shilling monthly instalments.**

*Man who was described as being "Down and out."*

There was a general amazement in Mr. Justice M. L. Tew's Court on Monday, the 5th November, 1928, when an order was made to the effect that one J. P. Dawodu was to pay Alfred P. da Costa ( judgment creditor ) the sum of £163 with £5 3s. od. costs by one shilling monthly instalments.

Dawodu who was represented by Mr. M. N. Bright-Wilson was described as an insolvent debtor having various claims and judgments against him. Mr. Wilson said further that he ( Dawodu ) had to pay a series of instalments to his creditors according to various judgments of the Court entered against him.

He was down and out and was unable to pay these series of instalments. He had applied to several places for work and failed. He was at one time a prosperous man with business worth thousands of pounds but for some years he had met with a reverse of fortune.

In ordering payment at the rate of one shilling a month, His Honour observed that the order was made so that the judgment debtor might not forget the debt.—*The Nigerian Daily Times*

271 years to pay a debt.

ARRIVAL.

Town Councillor J. Bagan Benjamin, C.E., A.M.I.C.E., who had gone to Ẹpẹ on Professional Engagement, arrived Lagos on Friday morning, the 2nd instant.

ON LEAVE.

Rev. C. A. Sowunmi, M.A., Curate of St. Paul's Church, Breadfruit, is on a month's leave, with effect from the 5th November, 1928.

OLUṢAKIN.

## ITAN IṢẸDALẸ AWỌN FILANI.

*( Ẹda ọrọ Ọgbẹni Hethersett.)*

LATI ỌWỌ KEKERE-AWO.

Si Oniwe Irohin *Eko Akete*.

Mo bẹrẹ f'oji,

Laiṣiyemeji ẹniti o nka iwe yi ti ngbọ oruko awọn Filani ri, iṣe wọn ni ilẹ Ijọba Yoruba, ati ohun ti nwọn fi oju awọn babanla wa ri, nigbati nwọn di oluwa ilẹ wa,—ilẹ Yoruba.

Mo fẹ sọ itan iṣẹdale wọn fun nyin bi, a ti gbọ o. Nigbati Mohammadu ku Abubakare li o tẹle e. Lẹhin ti Abubakare ku Imoru li o tẹle e. Ni sã ti Imoru wa ni Olori awọn Musulumi, o ran olorukọ rẹ, Imoru kan, lọ si ilẹ kan lati lọ iṣe wasu. Ọkọ ni nwọn wọ lọ si ilẹ na.

O kọ Imoru na lati lọ wasu "Ọlọrun ni Ẹniti o yẹ lati ma Sin," ati pe, "Bi nwon ko ba fẹ gba ti Ọlọrun gbọ, ki o fun wọn ni ogun."

Nigbati Imoru de ilẹ na ti o joko o ran awọn miran lọ si igbereko ilẹ na kakiri; nwọn gba ti Ọlọrun li ọna ti Mohammadu, nigbati o pẹ, lẹhin ọdun pupọ. Imoru ti *Mecca* ranṣẹ wa pe Imoru ti o ran wa iṣe iwasu ni ilẹ ti a wi, lati pada wa *Mecca*. Nigbati o nfẹ lọ, Ọba ilẹ na ni "Tani o yan silẹ ti yio ma ṣe iwasu fun wa"? Imoru ranṣẹ lọ ipe ọkan ninu awọn ti o fi si igbereko wa si

ibiti on na ti wa ; on si lọ si *Mecca* lọ ijẹ ipe Olori rẹ. Awọn ara ilẹ na mọ ọwọ Alufa na ti o rọpo Imoru, nwọn mọ ede rẹ. Lẹhin ọdun pupọ Ọba ilẹ na fi ọkan ninu awọn ọmọ-Ọba obinrin fun u lati fi iṣe obinrin. Lẹhin igba diẹ o bi ọmọ kan fun alufa yi. O to sa ti iba tọhun ; ṣugbọn ko fọhun, ko fọhun.

Iya rẹ tun bi ọmọ keji le e, nigbati ọmọ yi wa dagba ti o to ohun ifọ, on li o la eyi ọmọ agba li ohun ; nwọn sọ ede ti o ye awọn nikan, awọn meji nikan li o gbọ ede arawọn ; ede ti nwọn si nfọ na ni Filani. Bayi ni a gbọ itan iṣẹdalẹ tabi ipilẹṣẹ awọn enia Filani. Iwọnyi na ṣẹ niwọn ẹgbẹrun ọdun sẹhin.

Awọn Filani di Orilẹ-ede kan fun arawọn. Itumọ oruko Filani jasi (pupa) ; nwọn pe wọn bẹ lati ya wọn sọtọ kuro ninu awọn ti a npe ni *Negro* tabi Enia Dudu.

Nwọn kọ awọn ti awọn Hausa npe ni Bature, ti itumọ rẹ jasi 'Oyinbo', awọn ti nwọn ima ti iha gabasi wa si Odo-Ọya lati wa ṣe òwò ; *Egypt* tabi *Abgssinia* ni awọn wọnni ti nwa.

Awọn Filani yi ṣe iyanu niha yama *Africa* lẹrinkan, nwọn jẹ alaṣika Orilẹ-ede, larin ile ti o ni ẹtu loju bi agbegbe okun *Medisterranean*. Nwọn yatọ si Enia Dudu patapata, ni ri oju wọn ; ni ẹya arawọn ; irun ori wọn gun, oju wọn dabi awo pọkọ, nwọn jẹ koṣe-Oyinbo koṣe-Enia-Dudu. Ẹse wọn tin, nwọn ko ji kutukutu ṣe Musulumi ; bayi ni iṣẹdalẹ wọn. Nisisiyi a o sọfun nyin bi nwọn ti ṣe di Imale.

Ni ilẹ wa, nibiti ofin bi ti ilẹ Gẹsi ko si, alagbara li o ni aiye ; ohun ti o si wu wọn ni nwọn ima iṣe, ipa alagbara ki isi ini ayẹwo.

Awọn kan wa ti a npe ni *Saracen*, ti o si jasi Imale ; nwọn fi isin Imale lọ wọn pe ki nwọn di Imale : awọn Filani kọ. Awọn *Saracen* fun wọn li ogun, nwọn le wọn kuro ni ilẹ wọn ; nwọn le wọn kọja arin aṣalẹ nla ti *Africa*, ti a npe ni *Sahara*, si ilẹ kan ti a npe ni Fuladu. Nikẹhin nwọn fi agbara mu wọn gba isin Imale.

Nibiti nwọn sa si yi ni nwọn ngbe fun ọdun pupọ, ti nwọn ima da ẹran wọn kiri, nwọn ki isi iyọ ẹnikẹni lẹnu. Nwọn mbi si i, nwọn nrẹ si i, nwọn ntanka siha gabasi, nwọn nigba ọpọlọpọ ninu ilẹ ti a npe ni *Soudan*. Nwọn kọja iha Odo-Ọya siha ilẹ kan ti a npe ni Busa. *Borgu*, ati iha ariwa apa ilẹ Ijẹba Yoruba.

Awọn *Saracen* na ni o fi tulasin sọ wọn di Imalẹ, nwọn ko si tete fi Imale nwon ṣe ibi, tabi ma fi ṣe jadi tabi ọtẹ kiri. A o sọ bi awọn Filani ti ṣe bẹrẹ ogun ima gbe kakiri, fun nyin.

Ọkan ninu awọn Filani ni li a npe ni Sheik Othman, tabi Danfodio ; on ni o ru iwa ika ati isin ika ti Imale soke larin wọn, niwọn ọdun, A.D. 1750, on Danfodoi ; yi li o da ogun silẹ larin awọn Filani.

Bayi ni ogun awọn na ṣe bẹrẹ. Nwọn ni Danfodio ri irankan kan, pe Mohammadu farahan on, o wi bayi fun on pe, "Inu emi Mohammadu ko dun si ọlẹ ẹnyin Filani. Etiṣe ti ẹnyin mba awọn Keferi ṣe ọrẹ pọ, ti ẹ si joko jẹ pẹlu wọn baun ? Mo fẹ, mo si palhṣẹ, biobaṣepe Musulumi ba ni nyin, ẹ mu ida li ọwọ ọtun nyin, ki ẹ si mu Alkoran ni ọwọ osi pẹlu lawani, ki ẹ si gba ọkan awọn alaigbagbọ Keferi pada, nipa yiyi wọn pada si Igbagbọ Otitọ.

O pe apejọ, o rọ iran rẹ yi fun awọn enia rẹ. Lẹṣẹkanna, ti nwọn gbọ eyi, nwọn ranṣẹ si *Timbuctoo*, ati si ibi gbogbo ti awọn Filani tuka si, pe, ki nwọn ba wọn lọgan. Gbogbo wọn jẹ ipe Danfodio, nwọn pete ogun gẹ ; ko pẹ lẹhinna Danfodio bẹrẹ ogun.

Ohun ti Danfodio kọ ṣe ni titẹ ilu kan ti a npe ni Sokatudo, sarin aginju Aderi ; on li o si di olu ilu awọn Filani di oni oloni : o wa bẹrẹsi oye ijẹ larin awọn enia rẹ, o si nkọ wọn ni ogun. O fi asia funfun kọkan fun awọn Ijoye rẹ, ni ireti iṣẹgun ; o wi fun awọn pe, ẹ ma bẹrẹ gbogbo ijagun nyin ni orukọ *Allah* on Anabi Rẹ. O ki wọn laiya pe, Ọlọrun ti fi gbogbo ilẹ awọn Keferi ati ọrọ wọn tọrẹ fun nyin, pe, ẹnikẹni ti o ba ṣubu loju-ija gbogbo yio lọ si Ọrun rere tara.

Nipa ilere ati iyanju bi iru wọnyi ni nwọn bẹrẹsi kọlu ilu gbogbo nwọn nṣẹgun siwaju ati siwaju si i. A o sọ ohun ti nwọn ṣe nipa ogun yi diẹ, fun nyin.

Awọn Filani tete kọlu awọn Hausa, nwọn ṣẹgun gbogbo ilẹ wọn. Kubi ati Yanri, nwọn fọ awọn ilẹ mejeji yi pẹlu ; nwọn ṣẹ ilẹ Nufi, ati ile alagbara Burnu. Imale ni awọn Burnu ṣugbọn awọn Filani ko da wọn si ; nwọn fi wọn ṣe ijẹ.

Lati igba yi wa ni awọn Filani ti di paṣan apa ihahin *Africa*. Ilu gbogbo ni nwọn ngbe ogun kiri, ti nwọn nrun ilu kiri ; nwọn so gbogbo ilu di amọna, nwọn nko ilu ati ileti kiri ; nwọn nta gbogbo enia ti nwọn ko pa, li ẹru. Olori wọn li Sokatu ṣe ile ; oruko oye Olori na a ma jẹ *Emurel* Musulumi, ti o jasi, Olori ti awọn Olotọ.

On ni gbogbo awọn Ọba igbereko rẹ gbogbo njẹ orukọ oye wọn imọ. *Sultan* ti o jẹ li odun A.D. 1824, ni a npe ni Ali bẹn Belo, ti Oyinbo Alarinkiri arinlẹka kan, ti orukọ rẹ ijẹ Clapperton . a ọmọ-ọmọ Danfodio ti a wi na ni iṣe.

Ileri ti awọn Filani na ima iṣe ni pe, nwọn o ṣẹgun titi nwọn o fi fi ida wọn bọ omi okun. A ka ninu iwe *Dr. Barth* pe, nwọn mu ipinnu wọn na yi ṣẹ.

*Sultan Tkamba*, lati Ṣida, niwọn ọdun A.D. 1830, o ṣẹ gbogbo apa iha *Biafra* titi de ilẹ awọn Ibo, ni ipẹkun Odo-Ọya. O fọ gbogbo apa iha ibẹ

kanlẹ, o fi wọn ṣabẹ iru ẹru ; iyọ on òwó ni nwọn si fi nsin i.

*Dr. Barth* si tun sọ fun wa siwaju pe, ko simi ima gbe ogun ika na kakiri titi o fi sọ gbogbo ilẹ na di aboṣi ati talaka, tobẹ ti o jẹ pe owo-bode lọwọ ero, ati owo-ode lọwọ awọn ara ilu, ni o jẹki o ri owo ṣe ilu rẹ. Emir na le pupọ.

Lander, ẹwẹ, sọ fun wa pẹ, o bẹrẹsi isọ ilu wonyi ni, leni leji, niwọn ọdun 1830.

Awọn ara ile Nufi gba ara nwọn kuro labẹ isin rẹ. Ṣugbọn, ki a ma ba igba iṣẹgun wọn nṣo, niha g b o g b o ariwa ati gabasi Odo-Ọya wa labẹ wọn.

Ni sa yi Orilẹ-ede diẹ kinun ni iha ibẹ ni o le daka wọn kọ.

Emi ni ti nyin nitotọ,
KEKERE-AWO.

---

"EKUTE!" "IKA!!" (FINGER) ỌMỌ!!!

Nigbati a ba ti ri ara ẹni pẹ, boya o ni iye ọdun, lẹhin bibere ile ati ọna ara, wa a ma bere pe, "Ọmọde nkọ?" Nigbati awọn ọrẹ wọnyi ba si pade nile ọkan ninu awon mejeji, ti eyiti o ṣẹṣẹ ti idalẹ de ba si ri ti awon ọmọde nta kọṣọ kọṣọ kọṣọ kiri inu ile, a fi ifẹ bere pe, "tabi awọn ọmọ rẹ ni iwọnyi? Kaka ki ọrẹ ti o bimọ yi wipe awọn ọmọ mi ni a ni "Mo dupẹ lọwọ Ọọlrun, awọn "Ekute" ti o fun mi ni yẹn o!

2. Bi enia ba ku, ti a ba ndaro, rẹ ọmọ sa jasi ohun ti awa enia duda gbe ni lankẹ pupọ, a ma bere pe "lagbaja ti o ku ko fi ọmọ silẹ bi o?" Kaka ki nwọn sọ pe (iyẹn bi o ba bimọ ni o) "o fi ọmọ silẹ" nwọn a ni "o ni Ika" kan (tabi ju bẹ lọ) nilẹ!!! (Enia ha tilẹ le ku tan botiwu ki o lẹwa to, ki a ke ika rẹ pamọ? Ẹran tan lọja ni?!!!)

3. Yala ọkunrin ni tabi obinrin ti o ba jẹ onişina (panşuga) ti gbogbo enia si ti ri pe owo rẹ ni, ti iru ẹni bẹ bá darugbo laini ọmọ kan kan, nigbati enia yio ba ma daro rẹ, nwọn a ni, "ye, o ma şe o, Ọlọrun iba tilẹ fun lagbaja ni Ika kan! şe iba dun!"

On papa le ma sare nipa egbogi ati ajo loniruru ọna, a si ma wipe "nba jẹ ni Ika kan laiye!!"

Niti panṣaga? Şe ika mẹwa l'o mu waiye? Ki lo jẹ mẹsau yoku, ki o to ma tọrọ horo kan nigbati ilẹ şu tan? Olugbodi a ma ni ika mejila kẹ!

Bi Yoruba ba sọrọ loju ẹniti o pe on gbọ Yoruba inu iwe jẹki o farabalẹ ki o ma ba fi ijinlẹ ede gbe e ta, ọrọ ori oke ni nsọ nigbati alaigbọ ijinlẹ ede ro pe ọrọ pẹtẹlẹ l'o nsọ. Nigbati a ba gbọ Larinka tabi Ekute ati Ika (*Finger*) ni igbọ awọ, jẹki o ja ọ ninu pe ọrọ ti nwọn nsọ, ọrọ "Ọmọ" ni!!!

AGBEKẸ.

---

# NOTICE.

IN THE MATTER OF THE ESTATE OF

## AKINWUNMI AJOSE-ADEOGUN,

(Deceased).

*Pursuant to the Statute 22nd and 23rd Victoria Chapter 35, intituled "An Act to further amend the Law of Property and to relieve Trustees."*

Notice is hereby given that all creditors or other persons having claims or demands upon or against the estate of Akinwunmi Ajose-Adeogun late of 25, Agbojo Street, Idoluwo, Lagos, Nigeria, who died on the 9th day of July, 1919, intestate, and Letters of Administration of whose personal property were on the 9th day of August, 1928, granted by the Supreme Court of Nigeria to Akinola Ajose-Adeogun of 9, Ajose Court, Lagos aforesaid, are hereby required to send particulars of their debts, claims and demands in writing to me the undersigned, on or about the 30th day of November, 1928, after which day the Administrator will proceed to pay and distribute the assets of the said estate among the parties entitled thereto, having regard only to the claims of which he shall then have had notice and that he will not be liable for the assets or any part thereof, so distributed to any person or persons of whose debt, claim and demand he shall not then have had notice.

And all persons indebted to the said estate or holding any effects of the said deceased are hereby required to make immediate settlement or deliver the same to me.

Dated at Lagos this 15th day of October, 1228.

AKINOLA AJOSE-ADEOGUN,
*Administrator.*

**Disinfectant Soap of Unrivalled Quality**

Use Magnet Carbolic Soap in your home— it refreshes the skin and guards against infection. Made in three sizes, and obtainable everywhere.

# MAGNET

## Carbolic Soap Tablets




WEST AFRICAN SOAP COMPANY LIMITED, APAPA.

## *Use Yaro for your baby!*

All experienced mothers give testimony in praise of "Yaro" as an indispensable 'Preservative' for 'Babies' Yaro has no equal in suppressing those complaints which make infants feel uneasy, especially during their critical teething period. Trust Yaro for all infants' complaints and use it for your baby. Price per bottle 3/3d & 2/3d.

## *Increased health for 3/- only.*

"Life Tonic Tablet" imparts tone and vigour to the body, renews every atom of the flesh, prevents brain fatigue and brings indescribable comfort to all mental workers. Price 3/- per bottle.

## *A chance for female sufferers.*

Wireless Female Pills, the latest Scientific Discovery, have answered divers cases of functional complaints of disorders peculiar to women. These Pills serve as an effective fertiliser against barreness Give "Wireless Female Pills" a trial and prove its reliability.

Our Anti-Plague Disinfectant Fluid kills dangerous flies, bugs, cockroaches, etc., etc. 1/- and 1/6d per bottle.

### *Anti-Gon Pills.*

Get rid of veneareal diseases before they get rid of you by using Anti-Gon Pills—a reliable antisceptic against Gonorhea. 3/- per bottle.

WE ALSO STOCK:—

Glaxo (large and small sizes)
Vitafer—Brain Tonic
Walk Easy Anti-Rheumatic Salt 3/6 & 2/-
Pile Pills 1/6
Vibrona Wine 7/6
Lactogen
Kalzana
Effective Pile Remedy 7/6
Back and Kidney Pills 2/-
Zotal 1/6 & 2/6

*Obtainable at:—*

# IYIN OLUWA MEDICINE STORES

*Head Office:*—88, Broad Street, Lagos,
*Branches:*—6, Martins Street,
41, Alli Street, Faji Market,
27, Moloney Bridge Street
190, Griffith Street, Ebute Metta.

## White's Golden Male Tonic

(DOUBLE STRENGTH).

Whenever a woman has not been in the family way for a long time, the fault is usually set down to some disease or other in her generative organs.

Now while it is true that many women suffer from disease, yet many times the fault lies with the man, owing to weakness or some other disease of the male organs of generation. White's Golden Male Tonic (Double-Strength) is calculated to give full vigour to the man, and to remove all diseases which prevent breeding. Every sensible man ought to use two bottles every month, to cure or prevent weakness of the generative organs.

Made and sold only by VICTOR WHITE, Esq., *The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos.*
*N.B.*—NOT OBTAINABLE ELSEWHERE.
"Shake the Bottle."

AREMO FUN OKUNRIN.

Nigbati obinrin ko ba tete loyun, a ma nro pe ara obinrin na nikan ni arun wa. Sugbon nigba pupo ni o nje pe ara okunrin ni arun wa. Egbogi yi dara pupo fun Are, Eda ati gbogbo arun ti ki je ki okunrin se abiamo.

*N.B.*—O ye ki gbogbo okunrin ma lo igo meji-meji lososu—Ise ti egbogi na nse ni ara ko se royin.

Price TEN SHILLINGS (10s) per bottle.

*Postage 2/6 extra.*

## White's Golden Female Tonic

A splendid Remedy for Female diseases such as :—Barrenness, Weakness, Painfull and Irregular, Menstruation Leucorrhœa (Whites) Cramps, Ovarian, Neuralgia, Inflammation of the Ovaries. A Tendency to Miscarriage etc, etc.

Made and sold only by VICTOR WHITE Esq.
41, Offin Road, Lagos.
*N.B :—Not obtainable elsewhere.*

GBOGBONISE FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupo fun Aboyun, Iju, Eda, Aran, Oyun ti o ba fe baje, ati orisirisi arun mi ti ki je ki obinrin bimo.

PRICE 10/- PER BOTTLE.
Postage 2/6 extra.

WHITE'S
## WONDERFUL BRAIN TONIC.

This medicine stimulates and rebuilds the brain in such a way, that the regular user is able to do many times the usual amount of Brainwork that he used to do, before using it. To Brainworkers and those who have examinations to pass, it is a boon.

Made and sold only by SAMUEL VICTOR WHITE, Esq.
41, OFFIN ROAD, LAGOS.
Large size 5/- per bottle. Packing and Postage 2/6 extra.
Small size. 2/6 per bottle. Packing and Postage 1/6 extra.
N.B.—*Scholars should not be without it.*

EGBOGI ISOYE.

Egbogi yi dara pupo fun awon omo-ile-iwe awon ti o nfi iwe sise ati gbogbo awon ti o ba ni lati lo fun idanwo.

*Iba se omode tabi agbalagba.*

## White's Golden Blood Restorer

(*A Native preparation for Women.*)

This medicine is an excellent remedy or Insufficiency or Loss of the monthly courses, Tumour in the Womb, False Pregnancy, Catarrh of the Womb, Various Runnings or Morbid Discharges from the Womb (especially those that are long-standing).

Sick Headaches, Dizziness, etc., etc.

Made and sold only by
VICTOR WHITE, ESQ, *Chemist,*
The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos
"SHAKE THE BOTTLE".
Price TEN SHILLINGS (10/-) per bottle.
*Packing and Postage 2/6 extra, to any part of Nigeria.*

EGBOGI ILN EJE FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupo fun obinrin ti ko ba ri nkan osu re mo (lalai to aseko), nkan obinrin ti ko ba po to. Ase Ewure pipo'ju, Eda ti o ba gbo, Eyo, Oyunkoyun. Oyun ti ko ba dagba, Oyi, Esauri ni akoko hela, Aran ati Iju.

## HORSFIELD'S

The well known suppliers of all classes of goods under the registered Trade "ZODIAC" Mark.

Call and see our Agent and give your orders to:—

MR. MOSES O. COKER,
Port Novo Market Street, Lagos.

who has samples every mail of all the latest styles of fancy and other goods, including our REGISTERED Palm Tree and Feather Embroideries.

We supply everything.

J. J. HORSFIELD & CO.,
(Manchester) Limited,
65, George Street,
Manchester.

## GOOD MARKET.

Gonorrhea Specific, Moloke Mone, A. & D. Bula Matadi for health-restoring purposes: these Medicines are on sale at Mr. H. Campos's First Class Shop. 37, Odunlami Street, Lagos. The Specifie acts like Magic: has cured many obstinate cases, and *will cure yours just the same*, if any.

Cheap Goods! Superior Quality!! Quick Fortune!!!

*Cable Address*:—"WHITE LAGOS".

MR J. T. AKIREMI WHITE
P.O. Box 82
20, Balogun & Breadfruit Streets
or
41, Offin Road, Lagos.

## Indents House.

Import of General Lines
Export of Produce Commission Agencies undetaken.

Correspondence invited.

With over 22 years' experience in this line of business.

Mr White's well-known connexion with reliable Firms in Europe is a matter of common knowledge to his clients.

A Trial is Solicited.

When replying advertisers please mention *Eko Akete*

# TO LET.

## One Splendid Pleasure Car

No. L2754.

**Always at everybody's service at Tinubu Square.**

For Terms, Apply to —

A. B. Williams,
14, Bishop Street, Lagos.

**ILE OWO OYINBO**

# JOHN RADCLIFFE

## Ni No. 63, Ehingbeti, Eko.

—— : o : ——

Ile-owo ti o wuyi fun ọja meremere bi Ṣẹda, aṣọ Yọmin ati aṣọ ti a fi ẹlẹya Oyinbo gbaleti.

Ẹ wa bẹ orişirişi ọja wa wo ni Ile-owo wa titun to kọ si Ile Niger ni No. 63, Ẹhingbẹti.

Aṣọ lorişirişi ni aṣetejọ: aṣọ Ṣẹda ati Siliki mbẹ bi awọn wọnyi jẹ eyiti awọn onibara ṣa ti nwọn si ti sami si ra wọn. Aṣọ lami-titi ti a npe ni Ṣantọnu nkọlu 'ra wọn.

Agbalẹtu ni gbogbo ọja wa fun didara wọn.

Pọ ọ si ni owo wọn.

PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING PRESS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAM'S STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.